# NISISIYI NI ASIKO NA




"Nisisiyi ni akokò itẹwọgbà; kiyesi nisisiyi ni ọjọ igbala" (2 Korinti 6:2).

"Bi ẹṣẹ nyin ba ri bi ōdodó, nwọn o si fun bi ōjo-didì; bi nwọn pọn bi àlãri, nwọn o dadi irunagutan" (Isaiah 1:18).

"Jẹ ki enia buburu kọ ọna rẹ silẹ, ki ẹlẹṣẹ si kọ ironu rẹ silẹ: si jẹ ki o yipada si Oluwa, on o si ṣãnu fun u, ati si Ọlọrun wa, yio si fi jĩ li ọpọlọpọ" (Isaiah 55:7).

## IPO ENIA

"Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" (Romu 3:23).

"Ọkàn enia kún fun ètan jũ ohun gbogbo lọ, o si buru jayi! tani o le mọ o? Emi, Oluwa, ni iwa awai okan enia" (Jeremiah 17:9, 10).

"Gbogbo wa ti ṣina kirikiri be agutan, olukuluku wa tẹle ọna ara rẹ̀; Oluwa si ti mu aiṣedede wa gbogbo pade lara rẹ" (Isaiah 53:6).

## IDAJỌ SI DAJU

"Niwọn bi a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ̃kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ" (Heberu 9:27).

"Ṣugbọn a ti da ẹniti kò gbà a gbọ́ lẹjọ na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bíbi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ́. Eyi ni idajọ na pe, imọlẹ wá si aiye, awon enia si fẹ òkunkun jũ imọlẹ lọ nitoriti iṣẹ wọn buru" (Johannu 3:18, 19).



## ỌNAASALA KANṢOṢO

"Jesu wi fun u pe, Emi li ọna, ati otitọ, ati iye: kò si enikeni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipaṣẹ mi" (Johannu 14:6).

"Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti a ba gbọ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o ni iye ti kò nipẹkun, on kì yio si wá si idajọ; ṣugbọn o ti ré iku kọja bọ si iye" (Johannu 5:24).

"Bikoṣepe ẹnyin ronupiwada, gbogbo nyin ni yio ṣegbé bẹ̃ gẹgẹ (Luku 13:3).

"Ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro niu ẹṣẹ gbogbo (1 Johannu 1:7).

"Ṣugbọn li aisi igbagbọ́ ko ṣe iṣe lati wù u; nitori ẹniti o ba ntọ̀ Ọlọrun wá kò le sai gbagbọ́ pe o mbẹ, ati pe on ni oluṣesan fun awọn ti o fi are bale wá a" (Heberu 11:6).

## ẸBUN NI IGBALA

"Nitori ikú li ère ẹṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfe Ọlọrun ni ĩye ti ko nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa" (Romu 6:23).

"Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ĩye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

## ONIGBAGBỌ NI IYE AINIPẸKUN

"Nkan wọnyi ni mo kọwe rẽ si nyin ani si enyin ti o gbà orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ; ki ẹnyin

ki o le mọ̄ pe enyin ni iye ainipekun" (1 Johannu 5:13).

"Emi si fun wọn ni ìye ainipẹkun; nwọn ki o si ṣegbé lailai, kò si si ẹniti o le já wọn kuro li ọwọ́ mi" (Johannu 10:28).

## BI ENIA TISE LE PARUN

"Awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi ẹyi" (Heberu 2:3).

"Ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ̄ yio jẹbi" (Marku 16:16).

"Ẹniti kò ba si gba Ọmọ gbọ, kì yio ri ìye; ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ̀" (Johannu 3:36).

## RO NIPA IGBE AIYE ONIGBAGBO

"Ori awọn enia buburu li a o dà si ọrun apadi, ati gbogbo orilẹ-ède ti o gbagbe Ọlọrun. (Orin Dafidi 9:17).

"Bi a ba si ri ẹnikẹni ti a kò kọ orukọ rẹ sinu iwe ìye, a sọ ọ sinu adagun iná" (Ifihan 20:15).

**Word Of Truth**, P.O Box 1126, Kaduna, Nigeria